# ATUNSE IBEERE LATI INU IWE "ORE MI"

Omoluabi ati omo to se mu yangan ni Sola, salaye awon iwa re to fi eyi han.

Sola je olu eda-itan ninu iwe "Ore mi". Solayide ni apeja oruko re. Obinrin ni Sola ti a n soro re yii.

Sola je omoluabi, omo ti won ko nile ti o gbeko ti o si mu eko naa lo. Lati ibere iwe naa de opin ni a ti ri ka wi pe omo rere ati omoluabi ni.

Lara awon iwa ti o fi Sola han gege bi omoluabi ni ikini. A ri ka wi pe Sola maa n ki awon obi re bi o ba lo sile paapaa julo lori ikunle yato si Kunbi ti o maa n duro ki awon obi re. Nigba ti Sola ati Kunbi pade Femi ti o si ki won, Sola nikan ni o da Femi lohun, Kunbi ko dahun.

Sola je omo ti o koju mo eko re. Awon obi Sola ko lowo rara sugbon eyi ko ni ki o maa se isekuse kiri bi ti Kunbi ore re. Ile olowo ni Kunbi ti jade sugbon ko koju mowe re rara, okunrin ni o n tele kiri ti ko si pari koosi ti o n se ni Fasiti Afonja.

Lara awon iwa omoluabi ti Sola ni ni iteriba. O ni iteriba fun awon obi re ati awon miiran pelu. Iteriba yii han ninu iwa re si Femi, o si mu ki o wu Femi lati fe, yato si Kunbi ti ko ni iteriba fun baba re ati awon osise nile won. Aini iteriba Kunbi ni Femi fi koriira re.

Sola ko kegbekegbe, se isekuse tabi rin irinkurin. Yoruba bo won ni "Agutan to ba baja rin yoo je imi". Ko ri bee loro ti Sola. Alabagbe ni oun ati Kunbi ore si tun ni won. Gbogbo bi Kunbi se n tele okunrin kiri, ti o n fi ogba sile lojo eti pada lojo aje lati se faaji pelu awon okunrin, Sola ko

se bee rara. Koda o maa n gba Kunbi nimoran lati yi pada ki o ma ba a di apere ajase. Bi ko ba si ni ileewe ile awon obi re ni yoo wa.

Sola pa ara re mo di ojo igbeyawo. Eyi si je iwa omoluabi. Sola gan-an ni o ye lati maa ni ajosepo pelu awon okunrin lati le rowo sugbon ko figba kan ni ajosepo pelu okunrin. Femi ni eni akoko ti o fe, leyin ti Femi gbe niyawo ni won to ni ajosepo, ti Femi si ba nile.

Sola kii se olojukokoro, o ni itelorun. Owo ti awon obi re ba fun ati owo ti o n ri nibi oja to n ta lo n na. Ko se ojukokoro si owo Kunbi tabi owo elo miiran.

Omo ti o gbon ni Sola. O bere si ta oja peepeepe lati le ri owo kun owo ti awon obi re n fun. Ohun ti o n se yii je ona lati ran awon obi re lowo nigba ti o je wi pe talaka ni won. Dipo ki okunrin maa ba ni ajosepo lati fun lowo, o jagbon ati maa sowo lati rowo.

Alaaanu ni Sola. Bi o ti laaanu awon obi re naa lo n se fun araata. Aanu ti o ni lo mu maa ran awon obi re lowo nipa tita oja peepeepe lati rowo. Kii puro gbowo lowo won bakan naa. Aanu yii naa lo se ti o fi mu Femi lo sibi ti Femi beere lowo oun ati Kunbi, dipo ki o juwee ona fun Femi.

Sola kii wo asokaso. Opolopo akekoo lobinrin ni won maa n kegbekegbe nipa wiwo asokaso ni ileewe. Sola kii se eyi bii ti Kunbi ti o maa n woso ti yoo fi aya ati omu sile.

Eni ti o ni iberu Olorun ti o si maa n fi oro siro ara re ni Sola. Bibeli ni ki a nifee omolakeji gege bi ara wa. Sola ro wi pe Femi ni iyawo nile ni o fi so fun wi pe oun ko fe ba iyawo Femi du Femi nitori oun ko ni fe ki obinrin kankan ba oun du oko nigba ti o ba ya.